IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 728 THURSDAY, JUNE 2[illegible], 1964

## Okunrin Kan Jabo Ninu Oko Reluwe !

OTURKPO:— Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati oko reluwe kan nbo ti awon enia inu oko na bere si taku oro larin ara won ti okunrin kan, Johah Ede sesi jatile ninu oko na lori ere ni ojo isegun ti ise ojo ketalelogun osu yi.

Eniti oran na soju re fi ye wa pe, Ogbeni Johah Ede nlo si ilu keji lati lo wo iyawo re ti o sese bimo okunrin.

Awon ero inu oko reluwe na nsoro lori oro ekunwo owo osu eyiti Morgan pa lase pe ki Ijoba san fun awon osise.

Gbogbo won nso pe ponun medogun (£15) ni Igbimo Morgan so pe ki Ijoba maa san fun awon osise ti nwon ba sese bere ise sugbon ariyanjiyan wa fun awon enia na lori oro yi, eyiti o da ija sile.

O beni Ede si so fun won pe, eniti ko ba mo idi oro na daada ki o pa enu re mo, ki o ma sise soro le e ma. Lesekese ni awon yoku ba tuto soke ti nwon si fi oju gba a ni ija ba de, Awon enia na ko mo igbati nwon ti ara won de enu ona ti Ede si fi tabiti bo sile.

Lesekese ni ariwo ta ge! ti nwon si sare so fun awon alase oko reluwe ki oko na to duro. Nwon ti gbe ogbeni Ede lo si ile iwosan fun itoju. Ko ku sugbon o fi ara pa pupo.

# IJOBA KO TI SAN OWO OSU FUN AWON OSISE

## Okunrin Kan Ba Olopa Wo Gidigbo

EKO:— Oro di bi o lo o ya fun mi nigbati okunrin kan, Ogbeni Owolabi Olaniyi okan ninu awon osise Ile ise Minista Alamojuto eto ise fun Apapo Ijoba Naijiria lo bere owo osu re fun osu yi lodo Oga asanwo-osu ti ko si ri owo osu na gba sugbon bi nwon ti nso oro na lenu ni awon Olopa sare wole de ti nwon si ragabu okunrin na jade ni osan ana.

Irohin fi ye wa pe, ni ijeta ni ojo ti awon osise na nilati gba owo osu ti pe, gbogbo won si ti nreti lati gba owo won sugbon nwon ko ri owo na gba.

Nigbati nwon reti, ti eti si di sesere ni okunrin na ba mura lana ti o si lo si odo oga-asanwo won pe, "Bi o ko ba pe mi emi na o pe e r a mi. bi e ba gbagbe m i, emi alara ko ni gbagbe ara mi, mo de, owo osu mi da ?"

Sugbon n i g b a t i okunrin na so oro yi tan, ti o si nreti pe, o g a na yio fun on lowo ni oga na ba so fun un pe, "Owo ko ni si nile fun lati san."

Irohin fi ye wa pe, nwon pe kini na lowe, o ni aro ninu, ni awon mejeji ba beresi bu ara won ti awon ara ibi ise na si fi sare si ita lati wa dawon lekun Oro na, nigbati nwon be wo "gidigbo"

Sugbon awon Okunrin na ko ti dake bi awon enia ti nsipe fun won to, ti nwon fi ri awon Onisokoto penpe ti selewu etu riyeriye ti nwon si beresi na Okunrin na ni ponpo bi ejo-aye.

Sibe Okunrin yi ja butabuta, s u g b o n, "Enia mewa mu u, o bo lo, bi o se gbigbe nwon o gbe o. "lesekese ni awon Olopa a gbe Okunrin na

### "It'o Șe Gbe, O Șe Woo ! "



bi igi idana lati Ori Oke ile petesi meta bo si sale.

Nigbati awon Olopa na yio fi gbe Okunrin na dele, o fere di "okan -on Oguna" Sugbon bi nwon ti gbe Okunrin na dele, ti awon Olopa si tun nlu u, ni awon Osise ile ise na ba sare jade si awon Olopa ti won si nkigbe lohun rara pe.

"Eo ma p a a, omo enia le nse bayi, ni ilu ti Ijoba wa, e ma mo p a e."

Sugbo okan ninu awon Olopa na so fun awon enia na pe, "Awa paapa na ki ise channa tabi wee enia, ki ise wipe, a nfi iya je okunrin na nito ripe o bere owo osu re tabi o nba enia kan ja lenuise sugbon ohun ti a nlu u fun ni wipe, o ko lati jeki a mu on ni gbati a fe muu, eyiti o lodi si ofin.

Lesekese ni ti awon olopa gbe okunrin na de isale, ni nwon ba ju sinu moto won bi ano ewa.

Sugbon siwaju eyi, ki awon olopa na to gbe Ogbeni Olaniyi de isale, ni nwon ti fi ko ndo won dara si lara ti on na si nke bi "ele de inu oke"

Bi awon olopa ti gbe okunrin na sinu moto won tan ni nwon ba gbee lo si Tesan awon Olopa Okesuna

Agboroso awon Olopa kan se alaye fun oniwe irohin wa pe, boya okunrin na yio farahan ni iwaju adajo ni owuro yi lati so ti enu re sugbon bi a ba ti tun gbo oro na si, e o tun ma a gbo o.

Irohin fi ye wa pe, Oloye Festus Okotie-Eboh Minista Alamojuto eto inawo fun Apapo Ijoba Naijiria lo pase pe ki ile ise Banki Apapo Ijoba o ma ti san owo osu fun awon osise ti Morgan so pe ki Ijoba fun ni ekunwo owo osu.

Irohin na tun se alaye siwaju sii pe gbogbo awon osise ni nwon ti njowere ara wa sinu ile ise Banki na lati wa gba owo won sugbon awon osise Banki na nso fun won pe "Nwon ni ki a maa ti sanwo osu nyin, e maa lo"

A gbo wipe awon elomiran bu s e k u n, awon miran nse efe, awon miran nse yeye, nigbati nrerin agbara ati tulesi.

Ogbeni B Cardeso ti ise akowe agba on siro owo ile ise na ni a gbo pe o pase pe ki awon akowe asanwo na o da

WO OJU EWE KEFA

# IWE SI OLOTU

## Ọkan Na Ni Wa Ni Naijiria

Olotu mi ọwọn, jọwọ fun mi ni aye ranpẹ yi ninu iwe Irohin Imọlẹ rẹ oloyinmọmọ lati dupẹ pupọ ọwọ oloye Dokita M. I. Okpara fun ọna ti o gba ti o fi ṣe irinajo rẹ, eyiti o pe ni "Pade awọn enia, Iwọ Orun" pẹlu alafia laisi rogbodiyan, eyiti awọn kan ti lero pe yio ṣẹlẹ.

Idi pataki ti Dokita na fi ṣe ibẹwo Ipinlẹ na ni lati lọ ki awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ gẹgẹbi iṣẹ awọn enia iṣe olori ẹgbẹ Alakoso lati ri pe on nbẹ gbogbo agbe ti awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ wa wo ni Apapọ Naijiria.

Mo si ro pe irinajo Okpara ti o yori si rere yi yio jẹki awọn Alakoso Ipinlẹ yoku ni se ibẹwo kakiri Ipinlẹ Naijiria laipẹ. Nitori gẹgẹbi iṣẹ awọn olori wa nwọn ni ẹtọ lati ma lọ kakiri Ileto ki nwọn si ma gba awọn ara Ileto na ni iyanju ati nipa isọkan ilẹ Naijiria.



Dokita M. I Okpara

Ilẹ Naijiria ni agbara, o si tun je ilẹ isọkan ti o yẹ ki gbogbo wa ṣapọ nitori ọkan na ni gbogbo wa.

Oyẹ ki ọmọ Ibo le ma gbe ni Ipinlẹ Ariwa, ki ọmọ Hausa na le ma gbe ni Ilẹ Ibo, ki Yoruba na le ma gbe ni Ila Orun bakanna ni ki ọmọ Ibo na le gbe ni Iwọ Orun ki awọn Hausa na le ma gbe ni ilẹ Yoruba laisi iyara ẹni si ọtọ nitori ọmọ Iya kanna ni gbogbo wa, ede ni o kan yatọ

Kakiri Agbaiye ni nwọn fi oju rere wo wa gẹgẹbi Orilẹ-ede ti o ni irẹpọ ati isọkan ko yẹ ki a jẹki nwọn mọ pe Ipinlẹ marun ni o wa ni Orilẹ ede Naijiria.

Ni idi eyi mo lero pe awọn olori ilẹ yi toku yio se ibẹwo kakiri Ipinlẹ Naijiria laipẹ gẹgẹbi Okpara ti se ti ẹ fun apẹrẹ awọn ti o ku paapa ni asiko ti Ibo gbogbo si ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria ku si dẹdẹ.

Isọkan ati irẹpọ ni o yẹ iṣẹ wa Naijiria oro na di owo ẹnyin Agbagba ẹ se ko yẹ wa.

Emi ni
Latifu Babalola

ẸKO

## Alla Nfẹ Ile-Iwosan

Ẹdakun ẹran mi lọwọ lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa paapa awọn enia to wa ni ilu Alla lati bawa tun ilu wa ṣe, paapa lati ni Ile-iwosan ti awọn ọmọ ilu wa yio magbe awọn alaisan lọ.

Lati ọjọ ti mo ti gbọnju si ilu wa, ile-iwosan kanna lo wa ni eyiti owa ni ilu Ẹgbẹ, sugbọn o jina si ilu wa to busọ mejilelado-rin si ilu wa.

Mo bẹ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ki wọn ran wa lọwọ lati fun wa ni Ile-iwosan ni asiko yi, Nitoripe wahala nla ni a nse ki ato de ilu Ẹgbẹ, alaisan miran nku sinu ọkọ, alaboyun miran nbimọ soju ọna.

Mo tun bẹ awọn ti ọmọ ilu Alla na ki wọn jẹki a mura si idesiwaju ilu wa, ẹjẹ ki a fa ara wa lọwọ gẹ ẹbi awọn yoku ti nṣe

A nri ka pe ninu iwe pe, awọn ilu kan dawojọ nwọn kọ ile-iwosan ifiwe ranṣẹ ati bẹẹbẹ lọ ti awa na bale ṣe eleyi Ijọba yio wo wahala wa, nwọn asi ran wa lọwọ pẹlu

Owe Oyinbo kan sọ pe, ẹniti oba ran ara rẹ lọwọ ni awọn ogun ọrun ranlọwọ mo mọ pe, ti aba ran ara wa lowo Ijọba Ariwa ṣetan lati ran wa lowo.

Olotu ẹku iṣẹ o,

Emi ni,
R, A. Abikoye

Alla

## Ẹ Ran Iddo-Oro Lọwọ

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le ran mi lọwọ lati ba mi tẹ iwe mi jade ki awọn enia mi paapa awọn agbaagba to wa ni ilu Iddo Oro ki wọn jẹ ki a mura lati tun ilu wa ṣe, ki a si pari ija ti o wa ni ilu wa. nitoripe ẹtẹ awo na ni ẹtẹ Ọgbẹni.

Lati ọjọ ti ọlọ o ti dẹ aye ni awọn enia meji ti nmaja si oye ti o ba si ti bọ sọwọ ẹnikan ija yio si pari, ọtẹ paapa yio si tan, Ọrọ ti Akaabi Balẹ ti Ijọmu ko kan Elesle rara, awọn Yoruba ni o ma nkorin kan pe, ija lọbalọba ko ṣe dedi, ki olukuluku gbẹnu dani.

Adupẹ lọwọ Ọlọrun fun Anu rẹ lori Iddo Oro ati Ijọmu ti ọtẹ na tete tan, Asitun dupẹ lowọ awọn enia wọnyi:- Joshua Oladipọ, Rufus Aiikobi ati Joel Gbadegun fun ọgbọn ati oye ti awọn fi pari ija na.

Mo tun bẹ Bello ki o pe awọn enia rẹ jọ ki o bẹ wọn ki nwọn le pari ọtẹ na, nitoripe, bi ogiri ko ba la enu alanu koni ko si

Abọ mi rẹ o,
Emi ni,
Irẹpọdun

IDDO-ORO,

AWỌN EGBOGI ATAMATASE PATAKI TI O WA LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU ARUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU EKINI:-

SEDO – PAYAL



(IPARA BI ORI)

Je ojulowo egbogi lati fi se iwosan orisirisi arun awọn ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara ẹgẹbi ọwọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi didun nigbakugba inarun tabi akọ Inarun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela lapa apa Ara sisu Alefọ Ekusa lori ọmọde tabi agbalagba egbo ẹsẹ tabi Adaajina egbo ẹsẹ ati orisirisi awọn amodi tabi awọn arun ara omiran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI.

Dara pupọ julọ fun awọn ti amodi ti a daruko wọn si oke iwe yi ba nyọ lẹnu nitoripe iṣẹ rẹ ni lati ma mu gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" enia, san patapata a si ma a iṣẹ ribiribi ninu "oju" enia pelu. Awọn ti oju wọn a ma "nsu" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o bdai enipe nkaakan wa afara si oju wọn yio bẹrẹ si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyanju lati m[illegible] egbogi Jamani yi dede fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbọuṣẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbọnṣẹ dede lojojumọ tabi ti igbọnṣẹ wọn mn nle korokoro nipa bayi jẹdijedi a bẹrẹ si ma yọ wọn lẹnu bẹni o si dara fun lilo fun awọn onijẹdijedi pẹlu awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn rọbirọbi ti won nta kakiri Ṣọbu ilu Eko ati igberiko Bere won ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

BI O BA N

Iwe—Tite

FUN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe Igbeyawo

TETE KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

Mọdupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lago s.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TỌ AFOJUBA
Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ko si ri iyatọ

# Ẹçsan Ko Gbo Oogun

L ti Ọwọ HADJI Y, A, DISU, EKO

O pọ ninu awa ọmọ ti o npede "Ku owurọ, o jire bi" ti ko si mọ pe, ẹçsan ko gbọ oogun, Bi nwọn ba wa ni ipo kan ti o ni laari diẹ larin ile tabi larin ẹbi tabi ni adugbo tabi ni ilu, nwọn yio ma a şipa-şebi, nwọn yio si ma a fi ọ jiyọ,

Nwọn ko ni ni laakaye lati mọ pe, gbogbo ohun ti a ba şe loni, itan ni yio jẹ lọla,

Nwọn ko ni igbagbọ pe, işẹ mbọ lati wa jẹ abọ fun onişẹ, Nwọn ko ni igbagbọ pe, ẹni i o ba şe Ire. yio ri ire,

Ẹniti o ba si şe ibi, yio ri ibi laisi ani-ani,

Eyi;ni o jẹki awọn oni la kaye fi ni igbagbọ si i pe, ẹçsan ko gbọ oogun,

Ọpọlọpọ awọn alagbara ti nwọn ti lo agbara wọn, lọna aidara, ni igbẹhin aiye wọn buru ju iki egungun lẹ,

Melo-melo ni ojo ti o ti rọ ti ilẹ si ti fi mu,

Melo-melo ni awọn ọlọ-/a ti nwọn ti fi ọla jiyẹ ti igbẹhin aiye wọn si buru ju bi a ti şe le şe apejuwe lọ,

Awọn enia gidi ti nwọn nro, ki nwọn to şe e, ti ki i şe e tan ki nwọn to ro o, Ni nwọn si nşe ohun ti o dara igbẹhin aiye wọ ma a ndun ju oyin lọ.

Eyi fihan pe, ẹçsan mbọ Ẹniti o ba si şe ire, yio ri ire. Ẹniti o ba si şe buburu y:o ri ibi. Al gbin alubọsa ki o hu ẹfọ,

Ẹ jẹki a ma a şişẹ ire, ni gbogbo igba, pẹlu suruu Onişẹ buburu ni oma a nro ero buburu si enia.

Eyi ko dara rara o, Ẹ jẹki a ma a şe iranti ni igbagbogbo pe, akukọ yio kọ lẹhin alagbara lọjọ kan,

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 19) Ifẹ ti o ni lati ma ko awọn enia jọ yio şẹ loni, ohun kan ti iwọ ko nireti yio şelẹ si ọ loni pẹlu,

PISCES (Feb 20 - Mar 20) Ohun kan ti o ti nfi ori ti yio yọri si rere lọjọ oni. ki to wa gbajumọ işẹ rẹ nisişiyi ki o si wa mojuto alafia ararẹ,

ARIES (Mar 21 - April 20) Ọjọ oni dara ohun rere ni iwọ yio ma lepa rẹ loni awọn ọdọmọkunrin ninu awọn ẹbi rẹ ko ni ni ifẹ lati ri ọ soju şe suru ma se sọ ọ dija,

TAURUS (April 21-May 21) Ija ẹbi ti o nfẹ pari. maşe se dina pe ki ija na ma pari kaka bẹ nse ni ki o se iran ọwọ ki o le pari tọju gbogbo ohun to le mu alafia wa fun ọ. Alafia logun ọrọ.

GEMNI (May 22-June 21) Şọra rẹ ki o si ro o nipa jijẹ ohun si ọrọ kan ti ẹ nsọ lọwọ, iyara gaga le ba nkan jẹ edekoyede kekeke ti o wa larin ẹbi o yẹ ki ẹfi ori rẹ ti si ẹgbẹ kan ki o le yanju,

CANCER (Jun 22 July 23) Inawo yio pọ pupọ fun ọ loni nşe ni ki o yanju iye ti o wu ọ lati na loni sọtọ boya iwọ yio gba alejo o si le ri owo agbatẹlẹ nibi işẹ rẹ,

(LEO July 24-Ang 23) Awọn enia yio fe ki ojẹ aşiwaju fun wọn ki osi şọra nipa bi ba obinrin şe adehun, maşe pa akoko işẹ pọmọ akoko ere,

VIRGO (Aug 24-Sept 23) Ọkan rẹ koni fẹ lati lo asiko kan danu lori işẹ kan ti ko ni lari, igbadun pọ ninu faaji ile ohunkohun to wu ki ode sama mu suru.

LIBRA (Sept. 24-Oct. 23) Maşe fa ọta ọeni ki o maşe ba enikan jowu, ọrẹ rẹ kan tabi ẹbi to sunmọ ọ yio wa ọ nija, şe suru maşe ja ninn eyi ni ire wa fun ọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Maşe fi ohun kan silẹ ayafi ki o ti ro o jinlẹ ki o to şe ohun kan, o yẹ ki o li to jinlọ ki o ma ba ke abamọ

SAGITTARIUS (Nov 21-Dec 21) O tọ ki o ronu lati pari edekoyede ti o wa nilẹ idaduro yio de si iru aji kan ti o wa lẹsẹ rẹ iwọ yio gbọ irohin kan lati okan wa ti yio da arẹ bo ọ

CAPRICORN [Dec 22-Jan] Ọjọ oni ki i şe ọjọ ti enia ni lati gbajumọ işẹ pupọ ilọsiwaju yio wa larin ẹbi ati işẹ rẹ.


# Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin yọ De

Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

## 'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a şe ni pataki Fun „ARỌN KINIŞA" tabi LATANATAN ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹrakú tabi lati ma şe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba ti lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu sibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo şe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn anodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi ca ojẹ ni şọbu awọn

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
ATI NI AWỌN ŞỌBU IBADAN:—
IŞẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌ



# EGBOGI JEDIJED

BERE ,E BOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fihan gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gba wa lara re si nyọ o lẹnu nigbagbogbo.Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngbe şe igbọnsẹ, Arun Jẹdijẹdi jẹ okan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati şe iwosan rẹ patapata

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisiyi ti nwọn ma a pọ owo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun ni ole şe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lero wipe boyabi wọn ba lọ si ile lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omuşu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata,

Şugbọn awa o ro bẹ rara Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ ylo si tun bẹrẹ bakana Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna p ojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ pnlu ijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupọ pupọju nigbakugba Jẹdiẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omuşuqia t ta o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnsẹi tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o 'a jẹ bere egbo'T "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani şeşẹ wa idi rẹ kio si danwgi orişi mẹta ni daju wipe iwọ ylo bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafiow io de si ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbegi atata nigboro Naijiria yakejado bere ni ni:

NIGERIA MEDICINE STORES
4, Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STO S
8, Palmchurch Street, Lagos

LATI OJU EWE KEJI

ara ilu Ilogbo lara Eniti ko ti lowo ni, eniti ko ko Ile ko eniti o ti ni,anikun II o tubọ ngni, eyi mu ki nwọn fẹran Ige gidigidi Nigbati o de ori oye tan, o fi awọn aburo rẹ joye nwọn k le; nwọn na aṣẹ, nwọn ntẹriba fun nu ẹgẹbi aṣẹ baba wọn.

Nigbati o di ọdun keji ti o gori oye, lo to bi ọmọkunrin kan, osi sọ ọmọ na ni Babatunde (nitoripe Onilogbo baba wọn lio tun wa 'aiye). Ọmọ ti Ogbojulogun bi nigbati o nlọ si arin ajo lọjọ kini pada wa si ile gbogbo wọn wa nkọmọ lubọ o ndun yungba.

Bayi ni awọn ọmọ Onilogbo di olowo, ọlọla ati enia pataki ni a r i n ilu, Okiki wọn si kan yi aiye ka

Ki Ayunọrunbọ t o de nwọu ti tọju ohun ti nwọn ti ṣe leri fun un ki nwọn to mu ọna Ajiran p ọ n l'ọjọ kini. Ilọpo meji meji ohun ti nwọn si leri f u n Ayunọrunbọ ni nwọn fun. O dupẹ lọwọ wọn o ni.

Ẹnyin ọ m ọ Onilogbo, mo dupẹ, mo tun ọpẹ da ẹ ṣeun salubarika, modupẹ m o tọpẹ d a, Ẹpin ohun ti ẹ fun mi larin ara nyin, nko ni nwọn fi ṣe Ṣugbọn mo fẹ wa mọ daju bi ẹ o m u ileri nyin tabi ẹ ko ni mu ṣẹ ni. Edumare yio ran nyin lọwọ ohunkohun ti ẹ ba dawọle, rere ni yio maa jasi.

Ṣugbọn nko fẹ ki ẹgbagbe ọrọ baba nyin. Ẹmaa fẹran a r a nyin tinutinu. Eyi ti ko ni jẹki awọn ọmọ araiye le ri nyin g b e ṣe. Nisisiyi, ngo ma pada lọ. ara, emi Ayunọrunbọ, ẹ ye buburu ti nje lawujọ ajẹ ti ẹ tọ, ti ẹ ṣi ra ipo baba nyin, ni ẹ to le foju ganni mi. Oluwa ko lọra mi nyin

Kabiyesi, Ige A d u b i ẹlẹṣa okun iyanju t i ngo gba ọ ni pe, nkan ti awọn ijoye ati ilu ba nfẹ, ni ki o ma ba wọn f ẹ, m a ṣe lọwọ ninu ifi ofin Ọlọrun K'ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹṣẹ, eniti o ba ni ki omaṣe turẹ, iṣe rẹ ko ni ṣoju rẹ.

Ẹbẹra lọ, o dọjọ miran ọjọ rere. O poora mọ wọn loju b ẹ a i Ayun-ọrun-bọ pada si AJIRAN.

Bayi ni mo pari itan yi, lagbara Odua, ngo ma sọ itan miran fun nyin, oruko itan yi ni IGBO EṢUBELEKE




Our tradition is based on principles of lasting validity: Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.



MERCEDES-BENZ

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

